*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# Ìgbésẹ̀ Méjì sí Ọ̀dọ̀ Jésù

Ọlọ́run fún gbogbo ẹ̀dá ní ẹ̀bùn tí ó tóbi jùlọ – Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kún. Ó fi fún wa nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, kí a lè yè bọ́ àwọn àbájáde ẹ̀ṣẹ̀ wa, kí a má sì dojúkọ ìdájọ́ adágún iná tí yóò wà títí aiyéraiyé, nígbẹ̀yìn (Jòhánù 3: 16, Róòmù 6:23). Tí o kò bá tíì gba Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, ní òye pé, olúkúlùkù wa ní ibi tí a máa lọ tí ìrìn-àjò wa láiyé bá ti dé òpin. Ọ̀run, tàbí ọ̀run àpáàdì ni ibi tí à ń sọ yìí. Ọ̀run jẹ́ ibi ayọ̀ tí kò lópin. Ṣùgbọ́n Bíbélì ṣàpèjúwe ọ̀run àpáàdì pé ó jẹ́ ibi ìdálóró tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà (Mátíù 13:41-42). Ọ̀nà kan ṣoṣo láti yè bọ́ ọ̀run àpáàdì ni, kí a gba Ẹ̀bùn Ọ̀fẹ́ Ìyè Àìnípẹ̀kun tí Ọlọ́run fún wa. Nípasẹ̀ ìgbésẹ̀ tó rọrùn méjì ni a lè gba Ẹ̀bùn iyebíye yìí:



## Ìgbésẹ̀ Kìíní: Ní òye pé o nílò Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kun

**Òtítọ́ Nípa Ẹ̀ṣẹ̀:** Ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ ohunkóhun tí a bá ṣe tí kò dùn mọ́ Ọlọ́run nínú. Ìjìyà fún Ẹ̀ṣẹ̀ sì ni Ikú Tẹ̀mí (ìpò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run). Ikú Tẹ̀mí Ádámù àti Éfà bọ́ sórí i gbogbo ẹ̀dá (Róòmù 5:12). Nítorí ìdí èyí, gbogbo wa ni a bí pẹ̀lú ìtẹ̀sí àdánidá láti dẹ́ṣẹ̀, a ó sì dojúkọ àbájáde ẹ̀ṣẹ wa bí a kò bá ní ìgbàlà. Yàtọ̀ sí pé àwọn tí ó kọ ìgbàlà wà ní ìpò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run; Ọlọ́run yóò jù wọ́n sínú adágún iná ní Ọjọ́ Ìdájọ́, pẹ̀lú, níbi tí wọ́n yóò ti jìyà ìrora tí kò ṣeé fara dà, títí láí (Máàkù 9:43-48). Ọ̀nà kan ṣoṣo láti wà ní ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run kí a lè yè bọ́ ìdájọ́ ìdálóró aiyéraiyé, ni kí a di àtúnbí.

Jésù wípé: *"Lóòótọ́ lóòótọ́ ni Mo wí*



*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



Ìgbésẹ̀ Méjì sí Ọ̀dọ̀ Jésù

Ọlọ́run fún gbogbo ẹ̀dá ní ẹ̀bùn tí ó tóbi jùlọ – Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kún. Ó fi fún wa nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, kí a lè yè bọ́ àwọn àbájáde ẹ̀ṣẹ̀ wa, kí a má sì dojúkọ ìdájọ́ adágún iná tí yóò wà títí aiyéraiyé, nígbẹ̀yìn (Jòhánù 3: 16, Róòmù 6:23). Tí o kò bá tíì gba Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, ní òye pé, olúkúlùkù wa ní ibi tí a máa lọ tí ìrìn-àjò wa láiyé bá ti dé òpin. Ọ̀run, tàbí ọ̀run àpáàdì ni ibi tí à ń sọ yìí. Ọ̀run jẹ́ ibi ayọ̀ tí kò lópin. Ṣùgbọ́n Bíbélì ṣàpèjúwe ọ̀run àpáàdì pé ó jẹ́ ibi ìdálóró tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà (Mátíù 13:41-42). Ọ̀nà kan ṣoṣo láti yè bọ́ ọ̀run àpáàdì ni, kí a gba Ẹ̀bùn Ọ̀fẹ́ Ìyè Àìnípẹ̀kun tí Ọlọ́run fún wa. Nípasẹ̀ ìgbésẹ̀ tó rọrùn méjì ni a lè gba Ẹ̀bùn iyebíye yìí:

2

Ìgbésẹ̀ Kìíní: Ní òye pé o nílò Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kun

Òtítọ́ Nípa Ẹ̀ṣẹ̀: Ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ ohunkóhun tí a bá ṣe tí kò dùn mọ́ Ọlọ́run nínú. Ìjìyà fún Ẹ̀ṣẹ̀ sì ni Ikú Tẹ̀mí (ìpò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run). Ikú Tẹ̀mí Ádámù àti Éfà bọ́ sórí i gbogbo ẹ̀dá (Róòmù 5:12). Nítorí ìdí èyí, gbogbo wa ni a bí pẹ̀lú ìtẹ̀sí àdánidá láti dẹ́ṣẹ̀, a ó sì dojúkọ àbájáde ẹ̀ṣẹ wa bí a kò bá ní ìgbàlà. Yàtọ̀ sí pé àwọn tí ó kọ ìgbàlà wà ní ìpò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run; Ọlọ́run yóò jù wọ́n sínú adágún iná ní Ọjọ́ Ìdájọ́, pẹ̀lú, níbi tí wọ́n yóò ti jìyà ìrora tí kò ṣeé fara dà, títí láí (Máàkù 9:43-48). Ọ̀nà kan ṣoṣo láti wà ní ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run kí a lè yè bọ́ ìdájọ́ ìdálóró aiyéraiyé, ni kí a di àtúnbí.

Jésù wípé: *"Lóòótọ́ lóòótọ́ ni Mo wí*

3

*fún ọ, bí kò ṣe pé ènìyàn di Àtúnbí, òun kò lè rí Ìjọba Ọlọ́run." ~ Jòhánù 3:3*

*Ìbí ti Ara* wà. *Ìbí ti Ẹ̀mí* sì wà. *Àtúnbí* túmọ̀ sí pé, Ọlọ́run bí ènìyàn ní ìgbà kejì (nípa ti ẹ̀mí). Èyí yàtọ̀ sí ìbí nípasẹ̀ ìyá ènìyàn ní ìgbà kìíní (nípa ti ara).

**Ní òye pé Jésù Krístì ni Olúwa àti Olùgbàlà:** O kò lè ṣe ohun tí ó dára tó, láti mú inú Ọlọ́run dùn nípasẹ̀ agbára àti ìwà rẹ, nìkan. Ọlọ́run rán Ọmọ bíbí Rẹ̀ kan ṣoṣo, Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀bùn sí ọ. Krístì kú lórí àgbélébùú láti san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú, kí o má bàa dojúkọ àbájáde àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà. Nípasẹ̀ Rẹ̀ nìkan ni a lè yè bọ́ àbájáde ẹ̀ṣẹ̀.

*Nítorí Ọlọ́run fẹ́ aráyé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́, tí ó fi Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo fúnni, kí ẹnikẹ́ni tí*



*ó bá gbà á gbọ́ má bà ṣègbé, ṣùgbọ́n kí ó ní Ìyè Àìnípẹ̀kun ." ~ Jòhánù 3:16*

**Jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́, kí o sì múra láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ:** O ní láti kọ́kọ́ gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́, láti gba Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ; kí o sì gbà pé o kò ní agbára láti gba ara rẹ là. Kódà, àwọn iṣẹ́ rere rẹ kò lè sọ ẹ́ di olódodo ní ojú Ọlọ́run. Ó ṣe pàtàkì láti gbà pé Krístì ti san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Bákan náà, ó ṣe pàtàkì kí o múra tán láti ronúpìwàdà gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

**Ìgbésẹ̀ Kejì: Jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ**

Kò ní ná ẹ ní nǹkankan láti ní ìgbàlà. O kò lè ṣe ohunkóhun tí ó dára tó láti ní ìgbàlà. Nípa oore-ọ̀fẹ́ nìkan, àti nípasẹ̀ ìgbàgbọ́ rẹ ni ìwọ́ yóò ri gbà (Éfésù 2:8-9). Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu



rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Róòmù 10:9). Sọ àdúrà yìí látọkànwá, láti gba Jésù Krístì.

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*

Ìwọ yóò di ọmọ Ọlọ́run Gíga Jùlọ tí o bá gbe àwọn ìgbésẹ̀ méjì wọ̀nyí (Jòhánù 1:12-13). Ìwọ yóò sì jẹ́: Alábápín nínú ogún àwọn ènìyàn mímọ́ Ọlọ́run nínú



ìjọba ìmọ́lẹ̀; ará ẹgbẹ́ àlùfáà aládé; ẹni tí a rà ní iyebíye, tí a sì fi èdìdì dì pẹ̀lú Ẹ̀mí Mímọ́.

**Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!



*fún ọ, bí kò ṣe pé ènìyàn di Àtúnbí, òun kò lè rí Ìjọba Ọlọ́run." ~ Jòhánù 3:3*

*Ìbí ti Ara* wà. *Ìbí ti Ẹ̀mí* sì wà. *Àtúnbí* túmọ̀ sí pé, Ọlọ́run bí ènìyàn ní ìgbà kejì (nípa ti ẹ̀mí). Èyí yàtọ̀ sí ìbí nípasẹ̀ ìyá ènìyàn ní ìgbà kìíní (nípa ti ara).

**Ní òye pé Jésù Krístì ni Olúwa àti Olùgbàlà:** O kò lè ṣe ohun tí ó dára tó, láti mú inú Ọlọ́run dùn nípasẹ̀ agbára àti ìwà rẹ, nìkan. Ọlọ́run rán Ọmọ bíbí Rẹ̀ kan ṣoṣo, Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀bùn sí ọ. Krístì kú lórí àgbélébùú láti san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú, kí o má bàa dojúkọ àbájáde àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà. Nípasẹ̀ Rẹ̀ nìkan ni a lè yè bọ́ àbájáde ẹ̀ṣẹ̀.

*Nítorí Ọlọ́run fẹ́ aráyé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́, tí ó fi Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo fúnni, kí ẹnikẹ́ni tí*

4

*ó bá gbà á gbọ́ má bà ṣègbé, ṣùgbọ́n kí ó ní Ìyè Àìnípẹ̀kun ." ~ Jòhánù 3:16*

**Jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́, kí o sì múra láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ:** O ní láti kọ́kọ́ gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́, láti gba Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ; kí o sì gbà pé o kò ní agbára láti gba ara rẹ là. Kódà, àwọn iṣẹ́ rere rẹ kò lè sọ ẹ́ di olódodo ní ojú Ọlọ́run. Ó ṣe pàtàkì láti gbà pé Krístì ti san gbèse àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Bákan náà, ó ṣe pàtàkì kí o múra tán láti ronúpìwàdà gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

**Ìgbésẹ̀ Kejì: Jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ**

Kò ní ná ẹ ní nǹkankan láti ní ìgbàlà. O kò lè ṣe ohunkóhun tí ó dára tó láti ní ìgbàlà. Nípa oore-ọ̀fẹ́ nìkan, àti nípasẹ̀ ìgbàgbọ́ rẹ ni ìwọ́ yóò ri gbà (Éfésù 2:8-9). Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu

5

rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Róòmù 10:9). Sọ àdúrà yìí látọkànwá, láti gba Jésù Krístì.

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*

Ìwọ yóò di ọmọ Ọlọ́run Gíga Jùlọ tí o bá gbe àwọn ìgbésẹ̀ méjì wọ̀nyí (Jòhánù 1:12-13). Ìwọ yóò sì jẹ́: Alábápín nínú ogún àwọn ènìyàn mímọ́ Ọlọ́run nínú

6

ìjọba ìmọ́lẹ̀; ará ẹgbẹ́ àlùfáà aládé; ẹni tí a rà ní iyebíye, tí a sì fi èdìdì dì pẹ̀lú Ẹ̀mí Mímọ́.

**Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

7